# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN.—

"EMI YIO FI OHUN TỌ NDUN MAKUNNU HAN AWỌN ALAGBARA, NGO SI JẸ ALAGBAWI AWỌN ODI"—W. T. STEAD.

VOL. I. NO. 50. SATURDAY, JUNE 23, 1923. FOURPENCE.



ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Ọpọpo nla lẹmẹta lọsẹ. Awọ-sẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana to a si fi nṣe Erọ na mọlẹ bi ọsangangan. Ore, ly fi onlẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday*, *Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

**A. KESSLER.**

ILE OWO OYINBO GERMAN HAMBURG

Iwọ le ranṣẹ Erọ-Iranṣọ "*Mundlos*" ati "*Adler*," nibẹ be si ni Erọ-riran bata pẹlu

E to Ọgbẹni A. Kessler lọ ni 7 Labinjọ Lane, koro Williams Street

Mundlos on top Mundlos.



Mundlos on top Mundlos.

A nranṣẹ orisirişi ọja fun enia to tete nlọ nile ni *Nigeria*.

Ọja tiwa ya. A si ni ẹja wọnyi fun tita:—Ohun erọ orin, Awo-Abọmafo, Kẹkẹ-ologere t'Ọkunrin t'Obinrin, Waji.

E le ri Erọ Iranṣọ "*Mundlos*" ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Maşu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK
undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION
to

S. I. M. Johnson,
9, Stable Square
Phone 227 Lagos
P.O. Box 495

OGBENI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Katawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni onituru awon ohun [illegible] fun tita ni owo opolo gbogbo [illegible].

O ti ngbowo Iron Ise [illegible] lati [illegible] odun [illegible] di oni.

AT-RI [illegible] ni OGBENI na je [illegible] awon onisowo [illegible] ni ile Nigeria.

OKO tita wa ni owo pe o.

OGBENI DURO THOMAS
ONISOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Oja to de fun u lati ilu Germany fun tita: awon nkan Awo abomole, Cement, Akara ati opolopo oja miran.

Ę lo de ibę, Igbo-Akan 'mopa ni ohun to ni.

Bi e ba fę, e kowe si i, *Number* Apoti-Iwe rę ni Ile ipin iwe (*General Post Office.*) ni 374. *Number* fifi-ero manamana ba a soro (*Telephone*) ni 243.

Ę WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ogbeni D. B. OSUNTOLU, onisowo Olatrewaju
ni opolopo oja fun tita ni Şabu rę ni.
No. 44, Balogun Street, l'Eko.
Nino awon oja rę ni iwonyi:—Ikoko taba, Carpets
Panu skole, Aşo onituru Ileko, Baranje,
Olowonyo, Yomini, (*Satten*.)
Ati orişirişi nkan alala miran, Oja Ogbeni yi roju
o si lere nino, opoku-oyobi ni.
Ę lo ra ti nyin nibę.

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany) is just to hand at Mr. Duro Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!
AŞỌ NYIN FAYA, Ę LỌRAN
AŞỌ NYIN FAYA, Ę LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON
Ogbeni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awon IBUSUN mèrèmèrè onidę to şęşę de fun u pęlu awon MAŞINI iranşo ti a npe ni *Gritzner* ti ọlowo ati ti ęlęşę, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Oja rę 55, Ita Mase leti ita Faji, l'Eko.

Ifa mbę fun awon to ba tete lo ra tiwon nibę: owo yępęrę ni a nta wọn, bęni awon Oja na si "ka 'yin" to.

Ę lọ ba Àwúre nyin pade nibę.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

LAWYER A-FI'RU FỌNNA; DARANDAṢAN ẸIYẸ TI NMU'SAN!!!

Ni lọlọyi a gbọ pe *Lawyer* kan lọ kubẹ-kubẹ si ọdọ obinrin *Lawyer* ẹgbẹ rẹ kan, wara-were bi o ti de ile, bẹ ni a sọ pe ọkọ'lobinrin papa de; kinni odigun obinrin yi ṣe? Afara o ti fi alakọri *Lawyer* ọdaran na pamọ sẹhin ilẹkun, ṣugbọn *Lawyer* ọkọ'lobinrin yi ti mọ pe "irẹ nrun" bi o si ti nwo fofofo ni ile na bẹ ni oju on pẹlu ọdaran *Lawyer* yi ṣe mẹrin, iyoku di iregbe *Lawyer* ọdaran na tun nraye ro *Lawyer*: a gbọ pe o ni ṣe on ko lọ ba obinrin na ni ābẹ orule *Lawyer* ọkọ'lobinrin na, ati pe on ko si mọ obinrin na ni Alarede rẹ: obinrin-a-f'eku-kan-rẹ-ọmọ-meji yi si bẹrẹ si lọ ibosi pe ki awọn aladugbo wa gba on nitori awọn *Lawyer* meji ti o fẹ ja yi. Nigbati a bi alatojubọ *Lawyer* na lere ẹjọ, a gbọ pe o ni lotọ ni on tọ obinrin na wa, nitori ọrọ asọtẹlẹ ti nwọn ti sọ, ati pe on si fun u ni pọun meji (£2) ti o si gba bakanna; obinrin na si jẹri si eyi o si wipe bi *Lawyer* ọkọ on ba fẹ ki o ma wa wo ọmọ rẹ, on ko dẹ ṣe mọ o! a gbọ pe ọrẹ ni awọn *Lawyer* mejeji yi, ti nwọn njẹ ara wọn lẹsẹ ẹhin bayi. Eyi ma ṣe kelebọ o! B'ẹja ba sun ẹja a f'ẹja jẹ.!!!

AWỌN OYINBO TO GBE'LE GBỌFA LAI R'OGUN.

Ninu ọsẹ to kọja, bi awọn oyinbo atukọ kan ninu ọkọ ogun titun kan ti *Franse* ti o wa ni ọsa mbi ti sa ọta agba s'orun a gbọ pe bi diẹ ninu awọn ọta na ti bọ silẹ bẹni ẹlẹgiri gbija, to si ṣe bi Oyinbo meje lẹṣe ninu awọn atukọ wọnyi, mẹta ku ninu wọn ni *Saturday* to kọja, ọkan tun ku lẹhinna, a si gbe wọn sin ni Ikoyi gẹgẹ bi a ti nsin oku jagunjagun. A ba Ọga'kọ yi ati awọn ara Oyinbo yi kẹdun ọfọ ojiji na.

AWỌN AKỌWE-ỌBA NGBARADI.

Awọn ẹgbẹ idapọ Akọwe-Ọba ṣe Ipade kan ni *Tuesday* ọsẹ yi ni Ile Iwe St. Peter lati da orukọ awọn enia ti wọn yio ran lọ si Ajọ Igbimọ Aṣofin ti *Nigeria* ro. Ọgbẹni H. S. Abiọdun Thomas ni alakoso Ipade na. Ọgbẹni J. T. Nelson Caulcrick si ni Akọwe rẹ.

IBA JẸ RI BẸ.?

O ta si wa leti fẹnrẹn pe Ọgbẹni Adebẹṣin Fọlarin *Lawyer*, ki yio lọ si Abẹokuta mọ fun Iṣẹ ti a ti pe e si ri, ati pe Ọgbẹni John O. George ni yio tun ma ba iṣẹ rẹ lọ gẹgẹ bi Onidajọ ni Kotu Ọmọ Ibilẹ ni Ake.

AWỌN IJỌ BROTHERHOOD MA DA NKAN NI'DE LAIPẸ

Ihin kan ni pe awọn Ijọ *Brotherhood* nibi, ma ṣe ariya Ọjọ-Ibi Alakoso wọn *Pastor* A. Adedeji Iṣọla, ẹniti o da Ijọ na silẹ, bẹrẹ lati *Sunday* ọjọ kinni oṣu to mbọ.

A o jihin yi ni kikun ni ọsẹ to mbọ.

MR. E. JENKINS HARRISON.
*BARRISTER-AT-LAW.*

We are greatly obliged to our country-man Mr. E. Jenkins Harrison Barrister-at-Law, for his Donation in aid of "Eko Akete," which he has so kindly forwarded us a fortnight ago.

## IFESI SI IWE TI LỌYA E. J. ALEX TAYLOR KỌ NIPA OHUN TI A WI LORI IDAJỌ TI A ṢE LARIN IJỌBA ATI OLUDEMI.

II.

A YI I SI EDE YORUBA LATI INU *Nigerian Law Journal* TI OṢU APRIL, 1923.

——:o:——

Awọn Ọgbẹni S. Thomas & Co., gẹgẹ bi a ti wi ṣaju, a ma fi owo lati ra ọja fun Oludemi gẹgẹ bi adehun wọn, o si ni lati ma fihan awọn ti o nra ọja fun nigbakugba iṣiro ọja ti o wa nilẹ fun wọn. Yala awọn ni tabi on na ni, bi nwọn ba fẹ ko ọja wa si Eko, le gba wagọnu (*waggon*) owo ti Oludemi gba kẹhin lọwọ S. Thomas & Co., jẹ ẹdẹgbẹrin pọnwun (£700) ni oṣu April, 1920, idunrin); iṣiro owo ti nwọn si pe e lẹjọ fun yi ni wọn ṣe ni oṣu December, 1920.

Iṣiro na sọ pe ọja ti o wa nilẹ jẹ tánún mejileladọta (52 tons). Ni oṣu February, 1921, eyini ni oṣu meji lẹhin ti nwọn ti gba iṣiro yi tan, nigbati Ejẹnti (*Agent*) wọn si lọ ko ọja na ni Abẹokuta, tánún mejidilọgbọn (28 tons) li o ba, Oludemi si ṣeleri pe on yio san iyoku, ṣugbọn awọn ti o nra ọja fun yi kọ, nwọn si lọ pe e lẹjọ ariri, ẹjọ na lọ si di ofo ti o si ja kulẹ yi loju idajọ Gẹsi ti o nran kedere bi idi.

Bi a ti tẹ idajọ ti a ṣe nibi ẹjọ Oludemi yi, ti a si sọrọ diẹ lori rẹ, ki ṣe pe ojukokoro owo li o ma wa sọ ohun ti a sọ, ohun ti o kan wa julọ nibẹ ni pe bi gbogbo aiye yio ti ṣe gba ni lọwọ awọn ika ati alarankan apenilẹjọ wonyi, ti nwọn ro pe ofin yio gbe fun wọn. Bi a ba lọ moju kuro, ti a si poṣe ṣara nigbati o yẹ ki a sọ ohun ti nbẹ ninu wa fa, ti a si nsọ pe ki Ọlọrun gba wa lọwọ agbako, o dabi igbati ọmọ-ọdọ sọ pe on arẹ ọmọ-ọwọ ti o nsunkun, ṣugbọn ti o si nfi ika ja a lekanna, ti o si nsọ fun u pe, "ọbọ nbọ." Iru ogbọn aṣekonijẹ bayi ko le wọ rara ni aiye ilaju yi o.

Ki a ma fa a gun lọ titi mọ, ki awọn ti yio ka iwe yi le ma fi ọkan ba ibiti a nsọ ọrọ wa si lọ, a fẹ to awọn iwe ti ẹni wa ijinni ninu ọgbọn kọ lẹsẹsẹ, eyiti a fẹ sọrọ le lori, ki a si fi bi o ti ri loju wa gbe e lẹsẹ.

1. Ọgbẹni Taylor sọ pe "pẹlu iyanu ati iwo tẹmẹ ni mo fi ka ohun ti Oniwe-irohin ọmọwe sọ nipa ẹjọ ti a ro, o jẹ iyanu, niti pe Oniwe-irohin na ri pe ẹjọ E. F. Oludemi ati ti Phillip Coker jọ ara wọn, mo ṣe ṣiọ si iyanju ofo rẹ pe ki a tun ofin na yẹwo nipa fifi keta penilẹjọ, ati ṣiṣi enia fi si ẹwọn," ati bẹ bẹ lọ.

Bi amofin (Lọya) Mr. Taylor ha fẹ sọ laiyẹwọ, pe ẹjọ Ezekiel Oludemi ati ti Phillip Coker ko jọ ara wọn? tabi o kan tilẹ sọ ọ ni ọrọ asọjẹ ni? kili a ṣẹṣẹ nto ẹjọ Phillip Coker bẹrẹbẹ lọ titi si ki a to sọ pe ẹjọ awọn mejeji ko jọ 'ra. Njẹ ki a wipe ẹnikan bura eke a si fi si ẹwọn, njẹ iwa rẹ san ju ti ẹniti o jale ti a si fi si ẹwọn bakan na? boya loju adanilẹjọ wa yi, ẹnikini ṣe olotọ pupọ nitoripe irọ lasan li o pa, ekeji si ṣe alaiṣotọ nitoripe o ji nkan gbe, ofin kan na kọ li a fi yanju ẹṣẹ awọn mejeyi? Ninu ofin, ẹṣẹ ole ni a npe ni lasẹni (*Larceny*) nibiti a ba to Fẹloni (*Felony*) iwakiwa si, ibẹ na ni lasẹni yio gbe wa. A fi Phillip Coker sun fun iwakiwa, (ẹṣẹ ti o tobi) niwaju awọn adajọ ti o jafafa, nwọn ro ẹjọ rẹ, o jẹbi nwọn fi si ẹwọn, o tun gbe ẹjọ na naro lori ẹbi ti nwọn ni o jẹ ati ẹwọn ti nwọn fi si, nwọn ko ti pe o jẹbi kuro lọna, nwọn si mu alebu ti o ta le oruko rere rẹ ati ọla rẹ kuro.

Nwọn fi Ezekiel Oludemi sun pe o ṣe Makaruru ninu iṣiro owo, loju ofin iru ẹṣẹ yi bọ si ọwọ ẹṣẹ iwakiwa bi ti Phillip Coker ti ri niwaju awọn adajọ ti o jafafa, nwọn ro ẹjọ rẹ, nwọn da a lẹbi, nwọn si fi s' ẹwọn, o tun gbe ẹjọ dide nipa ẹbi ti nwọn da a, nwọn ko ti pe o jẹbi kuro lọna, nwọn si mu abawọn ti o tale oruko rere ati ọla Oludemi kuro.

Nibo ha ni aijọra ẹjọ mejeji na wa? laiṣiyemeji, "akolekan pupọ li o mu ki ọkan pin yẹyẹ," bikosi ṣe bẹ, o le ṣe pe ọkan na ti fẹ ṣi ọrọ sọ tẹlẹtẹlẹ, tabi ẹjẹ ikunra ẹni loju lo pọ l' ori tobẹ ti o fi mọ mọ sẹ pe awọn ẹjọ mejeji ko jọ ara wọn.

Ọgbẹni Taylor sọ pe:—

2. "Ko si iyemeji rara pe Oludemi ṣe makaruru nibi ọja ti o fi ranṣẹ si awọn Ọgbẹni S. Thomas & Co., awọn ti nwọn nfun l'owo lati ra ọja, ni gasikia E. F. Oludemi gba pe on ṣe madaru ninu iṣiro owo ti on fi ranṣẹ, ati bẹ bẹ lọ. Lakoko yi, Ọgbẹni P. J. C. Thomas ẹniti o fun Oludemi ni iṣẹ lọ si Ilu Oyinbo (*England*) Kotu kikun si bere lọwọ ọlọgbọn Adajọ ti o gbọ ẹjọ wọn na pe ki o tilẹ wa ka iwe gbigbọ ẹjọ na ki awọn Kotu kikun ti ngbọ atunro tabi agbedide ẹjọ ni *Nigeria* le tun ẹjọ na yẹwo, nwọn si bere yala Ezekiel Oludemi jẹ akọwe ni tabi iranṣẹ awọn onişowo ti awọn Ọgbẹni S. Thomas & Co., ọlọgbọn Adajọ si ṣe bẹ, Kotu kikun ti ngbọ atunro ẹjọ si sọ pe ifisun Oludemi foriṣanpọn

( kuna ) lati fihan pe akowe tabi iranṣẹ S. Thomas & Co., ni Oludemi, nwọn si tutọ pe Oludemi ṣebi danu lẹnu patapata, lori idi ohun ti a wi yi, bẹni on li o jẹ koko ohun ti nwọn fi sun si." Ko si ẹniti ko mọ pe Agbẹjọro ti awọn Ọgbẹni S. Thomas & Co., ni Ọgbẹni Taylor, lotọ ni a fi le Agbẹjọro Ọba ( Attorney General ) lọwọ lati fi Oludemi sun laiṣiyemeji Ọgbẹni Taylor lo si Abẹokuta pẹlu iwe ẹjọ awọn ti agbẹjọro fun. Njẹ Ọgbẹni Taylor pẹlu iyi rẹ bi ọmọluwabi ki a mu ti yẹyẹ kuro, le sọ fun gbogbo enia pe lẹhin ti o ti gbọ ẹjọ awọn ti o fun ni ẹjọ ṣe tan, on papa ni inu ara rẹ lọhun ro pe ẹjọ wọn yi to tẹle? njẹ Ọgbẹni Taylor ko ti sọ fun ẹnikan ni akọbẹrẹ ẹjọ yi pe on ti sọ fun awọn ti o fun on ni ẹjọ ṣe pe nwọn ko ri ẹjọ ti o buru danindanin lati ba Oludemi ro.?

*Koi ti pari.*

---

## Man of the Week.

### THE REV. AMOS NATHANIEL COLE, WESLEYAN NATIVE MINISTER.

---

Born 1852; was at one time a Government Official, entered the ministry, 1891; laboured in almost all the circuits in the districts; appointed Superintendent of Olowogbowo Circuit, 1904–1914; transfered as Superintendent to the Faji Circuit, 1914, where he still labours: was appointed to preach the Centenary Sermon of the Society, 1913; is the only native minister of his persuasion, honoured to deliver an Ordination Charge on two occasions at Lagos; is at present the Senior Native Minister in active service in the Lagos district. Was requested to deliver an Address at the Memorial Service of the late Professor S. M. Harden, 1919; is an eloquent preacher and a ripe scholar. Was presented with a Congratulatory Address and a Purse by his Church (Wesleyan Tinubu) on his attaining his 70th Birthday in October last, June 18, 1923.

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Ki nto ma ba ọrọ mi bọ, o yẹ ki a ṣakiyesi awọn ọrọ ti a nlo fun orin ni ohun ilẹ wa

Iwa aitọ ti o wa fun awa enia dudu nipe ohun ti ẹlukuluku ba dawọle ni ṣiṣe nikan ni o nkun u loju, a ki si fẹ gbe iṣẹ ọm'ẹnikeji wa ga. Ninu awọn orin ni ohun ilẹ wa ti mo ti nba pade ti nwọn nlo kakiri oniruru ijọ, ọpọlọpọ ni ọrọ wọn wọ inu ara wọn. Ka ka ki ẹnikeji gba eyiti ẹnikini ṣe ( *Compose* ) yio yi ọrọ meji tabi mẹta pada ninu ẹsẹ kọkan, lẹhin na yio ma gbe fuja ti ẹniti o ṣe ( *Compose* ) iru ọrọ orin bẹ.

Ngo mu meji wa fun apẹrẹ.

Ekini—Ni iwọn ọdun kan ati abọ sẹhin ọdọmkọnrin kan ṣe orin kan pẹlu ọrọ rẹ eyiti ila kini ninu ẹsẹ kini orin na lọ bayi:—

"Baba to ni wa awa de"

Oṣu mẹfa lẹhin ti ọrọ orin na jade, ẹnikan tun dide lati wa ( *Compose* ) ọrọ fun ohun orin kanna Ila kinni ninu ẹsẹ kini orin na lọ bayi:—

"Baba aiyeraiye awa de"

Aye ko si lati to awọn ẹsẹ fun ohun orin kanna ti awọn mejeji ṣe sinu iwe yi lẹsẹ lẹsẹ ṣugbọn ẹniti o ba ri wọn, yio mọ bi o ti ri.

Apẹrẹ Keji—Orin kan tun jade eyiti ẹsẹ kinni lọ bayi:—

Ta lo lawa o ni Baba
Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ
Ọba Oluwa ni Baba wa
Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ.

Ni lọlọyi, ọrọ fun ohun orin kanna tun jade eyi ti ẹsẹ kinni lọ bayi:—

Ta lo lawa o m'Ọlọrun
Orere ẹ yọ ṣẹṣẹ
Ọlọrun l' Ẹlẹda wa
Orere, ẹ yọ ṣẹṣẹ

OYENẸYẸ.

Ajulọ ha pin sọdọ ẹnikan bi?—ED. E.A.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JUNE 23, 1923.

ỌBA NKI Ọ, ALAIYE NKI Ọ, BABA NKI Ọ.

Enia diẹ ni koiti gbọ pe George Ọba wa, Ọlọla-julọ ati Mary Aya rẹ ti sọrọ sinu Iwe ti a nfi sori Ẹrọ-Akọrin (*Gramophone Royal Messages*) eyiti Ọba *King* fi ki gbogbo aimọ'ye awọn ọmọ-ile'we to wa labẹ Asia rẹ ni gbogbo agbaiye nigbati a nṣe ariya Ọjọ-ibi Ọba Obinrin Victoria, Ibadi-aran nibi, ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu *May* to kọja.

George Ọba fi ọrọ tirẹ ninu *Record* na ṣọwọ si awọn ọmọ-kunrin, Mary, ẹwẹ, si fi tirẹ ṣọwọ si awọn ọmọ-binrin: ketekete ni a ngbọ ohun Ọba ati ti Ayaba bi nwọn ti nsọrọ nigbati awa papa fi *Record* na sori Ẹrọ-Akọrin kan ninu ọrọ ti Ọba sọ, o pe gbogbo wa ni "Ẹnyin enia mi" A!!! bawo ni ọrọ yi ti dun mọ ni to? Ọba *King* ko mọ enia dudu, pupa, funfun, tabi ayinrin yatọ ninu awa ti a ṣe orire lati wa labẹ Abo rẹ; o si da wa ni imọran pe ki a ni Ọgbọn ati Lakaye, ki a ṣe akọni, ki a ni inu're ki a ṣe olotọ, ki a ma si mọ ti ara wa nikan; laisi ani-ani, ijinmi ẹkọ niyi; bẹ na si ni Mary Ayaba ṣi awọn ọmobinrin lori pẹlu; Ẹ gbọ bi o ti wi "Ile ti o ba ntẹ atẹsiwaju ninu ohun-rere gbogbo, ti iwa Ile na si wa ni ailabawọn jẹ Ibugbe Ọlọrun" o tun sọ bayi pe "Ilekile ti o ba nṣe evi, iba jẹ ile olowo ni, tabi ti talaka o jẹ ile ribi-ribi lode aiye." Irufẹ awọn ọrọ-iṣiri yi nfi han ni pe, biotilẹ-jẹpe awọn Ọba wa jinna rere si wa ni ilu *Nigeria* nibi, sibẹ nwọn ko dẹkun ati ma ranṣẹ si wa pe ki a mọ dajudaju pe gbogbo wa ni itọju wa fun ninu Ijọba nla-nla yi; ojulowo ọrọ leyi, a si tanma pe yio jẹ ikilọ fun awọn Oyinbo miran ti iro inu wọn si awa Enia Dudu ko ju "epo kete, ala kete lọ"

A ṣọpẹ ati-ọkanwa fun Ọba *King* ati Ayaba fun ọrọ-ayọ ti nwọn fi ranṣẹ si ni yi, eyiti o jẹ akọṣe lati igbati a ti da ọjọ *Empire* silẹ; ki Ọlọrun Olodumare ma ṣai sun ẹmi tiwọn ati ti awa papa siwaju, latari anfani, ki a le gbadun wọn kalẹ.

Laipẹ, ao yi ọrọ na si ede wa fun anfani gbogbo awọn ọmọ-ile'we, ati ti awọn ẹlomiran, ao si tẹ wọn sinu Iwe yi.

Ẹ ba wa da Muso lẹmẹta fun Ọba *King* ati Mary Ayaba.

Muso! Muso!! Muṣo!!!

---

AṢEYI ṢAMỌDUN O.

---

ẸNI-ỌWỌ A.N. COLE, ALUFA OLOHUN IYỌ.

Gẹgẹbi a ti sọ ni lọlọyi, awọn "Dawodu" *Member Church Wesley* ti Ita Tinubu da bira kan fun Ẹni-ọwọ A. N. Cole, Alufa wọn eniti o di ẹni Adọrin ọdun ninu oṣu *October* eṣi, nipa fifun u ni Iwe-iyẹsi kan *Address* pẹlu Iwe-owo £20 (*Cheque*) lati ba a yọ ayọ ọjọ-ibi na. A ṣe Ipade-ẹyẹ yi ninu Ile-Isin Ita Tinubu ni agogo marun-abọ ọjọrọ *Monday* ọsẹ yi Ẹni-ọwọ O. J. Griffin lo ṣe alakoso Ipade na o si sọ ka-si-nkan ọrọ nipa ti Ẹni-ọwọ ti a nṣe ẹyẹ fun na gẹgebi o ti fi aiya ran iṣoro pupọ nitori Isin Kristi, ti o fi jẹ pe ni ọdun 1896, awọn Ẹgba fi ẹwọn gidigba kan si ọrun Ẹni-ọwọ yi nigbati o wa lẹnu Iṣẹ-Ọlọrun larin wọn, ni igboro Abẹokuta gẹgẹbi o ti jẹ pe nwọn ni o mu ami awọn Idahomi wa sibẹ: ọrọ ti ko jẹ otọ; Ẹni-ọwọ yi si fi esi ti o wu gbogbo enia to wa nibẹ lori, o si kin Ẹni-ọwọ alakoso na lẹhin ohun to sọ nipa rẹ, gẹgẹbi o ti jẹ pe nigbati awọn Ẹgba fi on sinu ẹwọn fun ọrọ ti on ko mọ idi tan, ti ọkan ninu wọn si nwa pọn ida ti o si fi ori sọrọ si on pe awọn Alagbara ilu ibẹ ferẹ ṣẹ on si ipa rẹ na!!! Ọgbẹni Alphonso Coker lo ka Iwe-iyẹsi na, Ogbẹni J. N. John lo si fi Iwe na fun Alakoso pẹlu Iwe owo na, ti Alakoso si fi fun Ẹni-ọwọ na. Ọgbẹni Peter J. C. Thomas si sọrọ gbe Alakoso lẹsẹ o si daba pe ki a ba Ẹni-ọwọ A. N. Cole sọ ọ pe, ki o ma ṣai bẹrẹ si kọ itan Igbesi-aiye rẹ nisisiyi, ki o si sọ gbogbo ohun ti o ti laja nitori Isin Ọlọrun ninu Kristi ni gbogbo ilu ti a ti ran a lọ ṣiṣẹ kini-kini, fun Ẹkọ awa enia isisiyi, o si sọpe pupọ itan ti alagba Ẹni-ọwọ na sọ eyiti Alakoso si jẹri si, jẹ ohun ti on ko mọ rara. Alakoso si gbe e lẹsẹ fun Imọran na: diẹ ninu awọn Agba *Church* Olowogbowo si wa sibi ẹyẹ yi: Ọgbẹni Alphonso Coker ni a yan ki o ka Iwe-iyẹsi yi, nigbati ara Akọwe gbogbo Ijọ na. Ọgbẹni

S. Ọladipọ Marsh, ko da, ṣugbọn, pẹlu aida ara la. Akọwe na wa nibẹ gbagba. Ori wa wu pupọ nigbati a ri ninu awọn ọmọ Ẹni-ọwọ yi ati awọn ibatan rẹ miran ti nwọn wa nibẹ nigbati Ijọ nbu ọla fun u bayi. Ipade tuka lẹhin ipari ẹyẹ ọjọ na, ni agogo meje fi iṣẹju mẹdogun kọja: olukuluku si lọ sile pẹlu ọpẹ nla si Olodumare ti o da wa si lati ri iru ọjọ na.

Ed.—"AKO AKETE."

---

## IYAWO ỌNA T'A FUN NI SISI T'O NM'ẸNU, ORI AIYELUJARA NI YIO F'ABỌ SI.

Iru aṣa ti a nri larin awọn Imale ilẹ yi jẹ aṣa kan ti o le ba ilu jẹ bi awọn to jẹ olori ninu isin na ko ba tete fi oju àgbà bẹ aṣa na wo. Aṣa na ti bẹrẹ nisinsiyi, o ṣẹ pẹ diẹ.

Bi o ba di akoko ọdun, iba ṣe Ileya tabi itunu Awẹ, awọn iyawo ọna a ma yanbọ iru aṣọ ti nwọn fẹ fun ọdun na fun awọn ọkọ ti o nfẹ wọn si ọna, bi awọn ọkọ wọn ko ba si ri iru aṣọ ti a yan fun ọdun yi, idamu yio ba gbogbo ẹbi ọkọ, nwọn a ma sure sihin sure sọhun bi eyi to gbe ọmọri-odo mì—iduro ko si, ibẹrẹ ko si. Bi o ba si ṣepe nipa airi owo, ọkọ ko le mu aṣọ yi wa, boya aya na le bọ lọwọ rẹ.

Lẹhin ti ọkọ ba ti fun iyawo ni aṣọ yi tan, yio tun fun aya rẹ ni owo ọdun, ṣugbọn bi owo na ba kere, iyawo yio kọ ọ patapata, a jẹ pe ajangoloto ọkọ na, o sọrọ, ko le ṣe bẹ mọ. Okun bata ja niyẹn, o di ọran suru—aya ma bọ lọwọ rẹ niyẹn.

Anu a ma ṣe ni lọpọlọpọ nigbati a ba ri awọn ẹbi ati ibatan miran ti nwọn ba nfi'mu sọkun kiri Shop, ti nwọn nwa aṣọ ti ko si ni ilu kiri—bẹni ọran 'yan ni. Iru eyi ha dara, a le ti ọmọ-ọlọmọ si gbese, ọjọ melo ni ẹ tilẹ ngbe nile awọn ọkọ na?

Oni-yigi eṣi miran ti parọ ọkọ to mẹta nisinsiyi—lori ka se onjẹ Awẹ leṣi, ka se irẹsi Keresimesi lọdun yi na, ni ẹ o ma yanbọ to yi si: *Igi ma da o!*

ADIRO-FẸHINTI.

## Diocese Girls Guild,

ST. PETER'S CHURCH,
ARẸMỌ, IBADAN.

1. The first anniversary of this Club was held on Sunday the 27th May, 1923, at 3.30 p.m.

A very inspiring sermon was preached by Revd. C. E. Doherty, B.A. after which some melodious airs were rendered by some of the members for which special mention must be made of Misses Oyekan Vaughan, Allen and Folarin.

We wish the Club more progress in all their efforts.

---

THE AFRICAN COMMUNION.
*Versus*
THE C.M.S.

Motion for Appeal to The Full Court in respect of the Judgment of The Court delivered by His Honour Sir F. A. Van der Meulen, Judge, on the 28th *ultimo* for the Defendants anent the Libel Action taken by the Plaintiffs against the Defendants has been successfully filed: the hearing of The Appeal will likely take place in August next.

---


## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awon iwe wọnyi ko ti si lode ni sā kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## Correspondence.

ABẸOKUTA.

DEAR EDITOR,

Please permit me a space in your most interesting journal. It would benefit the people of Oke Aleji if the authority of Egba Government would please see that there are Water-pipe, Street and Electric-light in Oke Aleji. Even if Street and Electric-light cannot be laid out, how is it that there is no Water-pipe: whereas we the Oke Alejis are paying its upkeep. And I don't see the reason why, that there must be no benefit to us.

I on behalf of several people interested implore that the wants of our people be satisfied, as this step will tend to erase the feeling of discontent against the powers that be. I think the Government will see to the matter in due course.

Thanking you very much MR. EDITOR for space allowed.

I am,

Yours faithfuly,

L. A. Ẹniọla Davies.

---

THE N.N. DEMOCRATIC PARTY AT EBUTE MẸTA.

The above party is taking Ebuta Mẹta Community by storm at 3 o'clock this afternoon by a Monster Meeting at Oyingbo Market for educating them with regard to the impending Legislative Council Election. Councillor J. Egerton Shyngle, Barister-at-law, Chairman of the party will preside supported by the Executive Council of the body and few others

## IGBẸ L' OWO WÀ.

LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£16—£16 10 fun *ton* kan

EPO.

£26—£26 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£27—28 fun *ton* kan bakanna.

---

KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—£14 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

---

DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa oriṣiriṣi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ ko, Ẹ lọ ri i.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja şowọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi:—
Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Igi Osun, Agbado. Iwo Malu, Awọ orişirişi,

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi irũ eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi işinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o jẹ onidẹ (Brass)

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi nınu *Motor Transport.*

## Preachers for To-morrow.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
6.30 p.m. do
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do do
9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) Rev. J. A. Cole
9 a.m. & 6.30 p.m. Holy Trinity (Ebute Ero.) Rev. S. J. Gansallo
9 a.m....St. David's (Jordan) Rev J. A. Leigh

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. Rev. D. A. Bababunmi
10.30 a.m. Ereko Bro. D. O. Mould
7 p.m. do. Bro. S. O. Stowe
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. A. N. Cole
7 p.m. do.
10.30 a.m. Ọbun Eko Rev. S. A. Pearse
7 p.m. Bro. E. E. Ajoṣẹ

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m. Jehovah Shalom T. D. Shaw
7 p.m. do. Rev. Suptd. G. A. Oke
9 a.m. Erelu do.
7 p.m. do. Bro. J. A. Laleyẹ
9 a.m. Bethel Rev. J. A. Wright
6.30 p.m. Bro. A. Olugbile
9 a.m. Zion Rev. N. J. D. Shomuji
6.30 p.m. do. do.
10.30 a.m. African Methodist Bro. J. A. Osohdi
4.30 p.m. Rev. I. O. Oyekunle

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m. Bro. J. O. John
30 p.m. Rev. J. K. Williams
a.m. Ararọmi (Baptist) Rev. A. A. Puddicombe
p.m. do.

**EBNEEZER (BAPTIST)**

a.m. Rev. E. C. Alabi
p.m. do.

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi Bro. A. Gbogboade
7 p.m. Pastor. A. Adedeji Iṣọla

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣẹ (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon ; Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Seservic at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service
John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrel and Edwin Matthew

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices This venture has already been opened bys them to the public at the aforesaid Station any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refresh ment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

## N. V. Handlemattschappij V.H.

J. F. SICK ati AWON EGBE.

No. 7, Ita Ibode lailai, Leti *Glover Memorial Hall,* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo, yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to bā lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ nimu MASINI na.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aşoju wa.

Ajeniluja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ogbẹni VIDAL R. COLE.

---

## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ijebu-Ode since 17 years ago.*

All Grammar School Lessons efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fees Ruled by the Readers:—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*
Readers I to III—3/- *per Quarter.*
Readers IV and V—6/- *per Quarter.*
Classes I to III—9/- *per Quarter.*
Boarding Fee—£1 2s. 6d. Monthly.

This is beside the Tuition Fee; and includes, Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services.

PLEASE NOTE:

Payments strictly in advance; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYO SORINOLU,
Iporo Ake, Abeokuta. *Principal & Proprietor.*

---

## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pętę, ilu nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owọ ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Eni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*
c/o Aafani Motors,
The Marina Lagos.

---

## JACOB A. AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWO."

Awo eso bata (*sole-leather*) ti a se daradara, ti o le ti o si pupa yo, ati Awo Hausa ni orisirisi awo, yala ni pupa, funfun, dudu, olefe, ati orisi awo miran ni a nta ni opoku oyoku.




Bi o ba fe wa wo Ile Awo nla yi, ti iru re ko si ni *Nigeria*, bi beko kowe sowo pelu owosi :—

E. B BEYIOKU-ALASE
168, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*. —Alawobata, Eko.

---

## All for Bicycles and Motors.

Ask for Kaduna Store,
No. 81, Odunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc, to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

Sam. A. Clay,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Odunfa St.
Lagos.

*Telegram Address*:—Kaduna Store,
81, Odunfa Street
Lagos

---

## "O ȘE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ogbeni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Are lodo Ijoba *Nigeria*, nta orisirisi oja ni Gbanjo, nile Gbanjo re ni 2, Isalegangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilę pelu.

Awon ojo oja-tita ni iwonyi. Monday, ati Thursday, lagogo mefa osan. Saturday, lagogo mesan aro, losose. O ntete san owo oja fun enia. Mu oja re lo si be.

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti e ba le lo si odo awon ti o polowo oja sinu Iwe-irohin yi, e jare e so po ninu Iwe-irohin Eko Akete ni e ti ri ipolowo oja na ka.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos. Writer and Lecturer.